“Gbogbo nnkan pẹlu kádàrá ni, titi dórí ikagara ati ijafafa, tàbí ijafafa ati ikagara”

Láti ọdọ Toowus, o sọ pe: Mo ba àwọn èèyàn kan nínú àwọn saabe ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti wọn maa n sọ pe gbogbo nǹkan pẹlú kadara ni, o sọ pe: Mo gbọ ti Abdullah ọmọ Umar- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- ti n sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Gbogbo nnkan pẹlu kádàrá ni, titi dórí ikagara ati ijafafa, tàbí ijafafa ati ikagara”.

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe gbogbo nnkan pẹlú kádàrá ni; Titi dórí ikagara, oun naa ni: Gbígbé ohun ti o jẹ dandan láti ṣe jù silẹ ati dídá ìgbà si i ati lilọ ọ lára tayọ asiko rẹ, ninu ọrọ ayé ati ti alukiyaamọ. Ati ijafafa, oun naa ni: Ijafafa ati ọgbọ́n nípa àwọn àlámọ̀rí ayé àti alukiyaamọ. Ati pe Ọlọhun ti O lágbára ti O gbọnngbọn ti kádàrá ikagara ati ijafafa ati gbogbo nǹkan, nǹkan kan ko nii ṣẹlẹ ni ayé àyàfi ki o ti ṣaaju ninu imọ Ọlọhun ati fifẹ Rẹ.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65039

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee